# ÀKỌ́RỌ̀ ATI ÀRỌ̀KÚRÒ ÒJÒ

## Joẹli 2:21-32; Iṣe Awọn Apọsteli 2:1-47

## ẸKỌ 66 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ọlọrun wipe, Yio si ṣe ni ikẹhin ọjọ, Emi o tú ninu Ẹmi mi jade sara enia gbogbo" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:17).**

### A ṣe Ileri Ayọ Nla

"Má bẹ̀ru, iwọ ilẹ; jẹ ki inu rẹ dùn, ki o si yọ̀." Ni akoko ti Joẹli kọ awọn ọrọ wọnyii silẹ awọn Ọmọ Israẹli fẹrẹ má ni ohun kan ti o ṣẹku ti wọn le yọ̀ le lori. Wọn ti fi Ọlọrun silẹ, wọn si ti kọ isin tootọ silẹ, idajọ Rẹ̀ si ti wá si ori wọn. Awọn ara Babiloni ti ṣẹgun awọn Ọmọ Israẹli wọn si ti sọ wọn di ẹrú. Eso oko wọn ti di gbigbẹ, awọn kòkoro si ti jẹ iba diẹ ti o tilẹ hù jade. Ṣugbọn Joẹli jẹ wolii Oluwa; Ọlọrun si n ti ipasẹ rẹ̀ kede igbà titun, akoko kan ti ibukun yoo tun pada wa.

Wo iru iyipada ti yoo wá sori ilẹ. Ọlọrun yoo rọ òjo, igi ọ̀pọtọ́ ti o ti gbẹ yoo si tun so eso; ajara yoo tun so eso – yoo pọ to bẹẹ ti àgbá nla gbogbo ki yoo le gba oje ti a o fun lati inu eso wọnni. Ọlọrun n bọ wa dá ohun wọnni ti kòkoro jewejewe ati iru kòkoro keji ti jẹ pada fun awọn eniyan naa. Eyi kò ha i ṣe ohun ti o gbọdọ mu ni kun fun ayọ̀ bi?

### Ọ̀dá ti Igba Isisiyii

Niwọn ọdun diẹ sẹyin, a ri ohun ti o ṣẹlẹ ni ilẹ Amẹrika nigba ti Ọlọrun sé ọrun ti òjo kò rọ̀. Apakan ni agbedemeji Iwọ-oorun di ibi ti a n pe ni Ilẹ Ekuru, awọn ohun ọgbin si kú. Awọn eniyan di alaini, wọn si fi oko wọn silẹ nitori wọn ko ri ounjẹ mu nibẹ mọ. Ijọba gbero orișirișì ọna lati fa omi wa si agbegbe yii, ṣugbọn wọn ko le ṣe aṣeyọri kan titi Ọlọrun fi rọ ojo silẹ. Ni akoko yii a n kà a pe ọpọ ọrọ̀ n ti ibi ti a n pe ni Ilẹ Ekuru lai pẹ jọjọ sẹyin, jade wa. Ojo ti rọ̀ lọpọlọpọ eso oko si ti sọ awọn eniyan ibẹ di ọlọrọ. A sọ fun wa pe ipinlẹ kan wa nibẹ ti o lọrọ ju ipinlẹkipinlẹ lọ ni gbogbo ilẹ Amẹrika bi a ba ṣiro rẹ ni ori kọọkan. Eyi fihàn fun wa ohun ti o maa n ṣẹlẹ nigba ti Ọlọrun ba se òjò mọ́ ọrun, ti ko jẹ ki o rọ̀, ati pe o wà ni ọwọ́ Rẹ̀ lati mu ọrọ̀ wá sori ilẹ.

### Akọrọ ati Arọkuro Òjo ti Ara

Wo o bi ọkàn Joẹli yoo ti maa wo ọna pẹlu ireti, gẹgẹ bi o ti n sọ fun awọn eniyan naa nipa ayọ̀ ti o wà niwaju wọn! O gba Ọrọ Ọlọrun gbọ́, o si le yọ̀ ni igbagbọ́.

Ni ibẹrẹ itan awọn Ju ojo akọrọ maa n rọ̀ nigba ti wọn ba n gbin awọn eso. Òjo si maa n rọ diẹdiẹ ni igba otutu; lẹyin eyi ṣaaju igba ikore, ni nnkan bi ọjọ kin-in-ni oṣu April, ọpọlọpọ ojo yoo rọ̀. Eyi ni a maa n pe ni ojo arọkuro, a si maa pese eso silẹ fun ikore. Ṣugbọn nitori ẹṣẹ awọn Ọmọ Israẹli, fun ọpọlọpọ ọdun ni o jẹ pe ojo diẹ ni kò rọ̀. Nisisiyii ileri naa ni pe ojo yoo tun rọ̀, yoo si tun mu igba ọtun wa sori ilẹ. Wò o bi eyi i ba ti mu inu wọn dun to!

### Òjo ti Ẹmi

Joẹli tun n sọrọ nipa iru ojo miiran, pẹlu. Awọn eniyan naa kò tun layọ mọ, nitori wọn ti kọ Ọlọrun silẹ; ṣugbọn nigba ti a ba tu Ẹmi Ọlọrun jade, orin iyin yoo maa ti inu ọkàn awọn ti o ri i gba jade. Eyi yoo jẹ ti gbogbo eniyan, ki i ṣe awọn alufaa nikan, awọn ti i ṣe aṣoju Ọlọrun fun eniyan ati aṣoju eniyan niwaju Ọlọrun. Ileri naa ni yi: "Emi o tú ninu Ẹmí mi jade sara enia gbogbo; ati awọn ọmọ nyin ọkunrin ati awọn ọmọ nyin obinrin yio ma sọtẹlẹ, awọn ọdọmọkunrin nyin yio si ma ri iran, awọn arugbo nyin yio si ma lá alá: Ati sara awọn ọmọ-ọdọ mi ọkunrin, ati sara awọn ọmọ-ọdọ mi obinrin li emi o tú ninu Ẹmi mi jade li ọjọ wọnni."

Wo bi ọkàn Joẹli yoo ti maa sọ soke fun ayọ̀ to gẹgẹ bi o ti n ro nipa itujade nlá nlà naa nipa ti ẹmi, ti o n bọ wá sori awọn eniyan! Gbogbo eniyan, arugbo ati ọdọ, ọlọrọ ati talaka, ọkunrin ati obinrin, ni yoo ni ipin ninu ibukun iyanu yii. Ẹmi ti Joẹli n sọrọ nipa rẹ ni ifiwọni Ẹmi Mimọ́, eyi ti o jẹ ohun iyanu to bẹẹ ti Peteru fi sọ fun ni pe awọn angẹli n fẹ́ lati wò (1 Peteru 1:12).

### Ẹkọ Jesu nipa Ẹmi Mimọ́

Fun ọpọlọpọ ọdun lẹyin ti Joẹli ti sọ asọtẹlẹ ayọ nla yii, awọn eniyan naa wà ninu ọgbẹlẹ sibẹ, bẹẹ ni a ko tu Ẹmi Ọlọrun jade sori wọn. Lẹyin eyi, ni ọjọ ayọ kan a bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu, ọkàn awọn eniyan si bẹrẹ si i yọ si iwaasu Rẹ̀. O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe Ijọba Oun ki i ṣe ti ayé yii. Oun ko le duro ti wọn ki Oun si wà lọdọ wọn nibi gbogbo ninu ara eniyan ti O gbe wọ̀; ṣugbọn nigba ti O ba pada si Ọrun, Oun yoo rán Olutunu miiran si wọn, ẹni ti O pè ni Ẹmi Otitọ. Oun yoo maa ba wọn gbe (bi ẹni kọọkan) titi laelae. Yoo jẹ Olukọni wọn, yoo si maa rán wọn leti ohun wọnni ti Jesu ti sọ fun wọn.

### Pẹntekọsti

Nigba ti akoko fẹrẹ to lati gba Jesu soke Ọrun, gẹgẹ bi O ti duro pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lori Oke Olifi, O wi fun wọn pe ki wọn pada lọ si Jerusalẹmu ki wọn si duro de ileri Baba, ti i ṣe ifiwọni Ẹmi Mimọ́. Ọgọfa eniyan si

gbọran si aṣẹ Rẹ̀. Wọn wà ni iyara oke, wọn si n gbadura tọkantọkan, gbogbo wọn si wà ni ọkàn kan titi idahun fi de. Ni Ọjọ Pẹntekọsti iró kan wá gẹgẹ bi ẹfufu lile, eyi ti o kún inu iyara ti wọn wà, Ẹmi Ọlọrun si bà le olukuluku wọn. Wọn si sọrọ ni èdè titun ti ki i ṣe eyi ti wọn ti mọ̀ ri.

Awọn eniyan lati gbogbo ilẹ Palẹstini ni o wà ni ilu naa ni ọjọ yii, awọn ti wọn ti wá si Jerusalẹmu lati pa ajọ Pẹntekọsti mọ́, wọn si n gbọ ti awọn ọmọ-ẹyin n sọ ède awọn ajeji eniyan. O yà wọ́n lẹnu pe awọn òpè ati alaikẹkọọ apẹja, bi awọn miiran ninu awọn ọmọ-ẹyin ti jẹ́, le maa sọrọ ni ède miiran. Ṣugbọn Ẹmi Mimọ́ Ọlọrun ni o n sọrọ jade lẹnu wọn. Eyi ni ami ti ode ara ti a fi mọ pe a ti fi Ẹmi Mimọ́ wọ wọn. Ohun kan ti o ṣe pataki ju eyi lọ ṣẹlẹ lẹsẹ kan naa: wọn gba agbara lati jẹ ẹlẹri! Jesu ti wi pe, "Ẹnyin ó gbà agbara, nigbati Ẹmi Mimọ́ ba bà le nyin: ẹ o si ma ṣe ẹlẹri mi ni Jerusalẹmu, ati ni gbogbo Judea, ati ni Samaria, ati titi de opin ilẹ aiye" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:8). Ẹmi Mimọ́ kò ba le awọn eniyan naa fun igbadun ti ara wọn, ṣugbọn ki wọn le jẹ ẹlẹri. A bukun wọn ki wọn ba le jẹ ibukun fun awọn ẹlomiran.

### Ẹri Peteru

Peteru, ẹda titun, ni o duro niwaju awọn eniyan nisisiyii. Nigba ti wọn fẹ kan Jesu mọ agbelebu, Peteru ti tiju lati jẹwọ pe oun mọ Ọn. Nigba ti angẹli nì sọ fun un pe Jesu ti jinde ninu oku o yà a lẹnu o si fẹrẹ má le gbagbọ́. Ṣugbọn nisisiyii o ti gba agbara, ẹ̀rù ko si bà a lati duro niwaju awọn Ju lati takò wọn pe awọn ni o pa Ọmọ Mimọ́ Ọlọrun. O wi fun wọn pe awọn ọmọ-ẹyin ko mu ọti yó bi awọn ẹlomiran ti rò, ṣugbọn wọn ti gba Ẹmi nì ti Joẹli ti sọtẹlẹ nipa rẹ̀ ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin. Joẹli wi pe, "ki o si yọ̀." Ayọ̀ awọn ti o ri Ẹmi Mimọ́ gba pọ rekọja. O kun inu wọn ni akunwọ silẹ. Peteru ko tun tiju Kristi ti oun ti sẹ́ lẹẹkan ri. Lẹẹmeji ninu asọtẹlẹ Joẹli ni Ọlọrun wi pe "Oju ki yio si tì awọn enia mi lai." Nigba ti Ẹmi Ọlọrun ba n gbe inu wa, a ki i fà sẹyin lati sọ fun awọn eniyan nipa Jesu Ẹni ti O gba ọkàn wa là ti O si n mu wa gbé inu ayé lai dẹṣẹ.

Nigba ti Ẹmi Ọlọrun ba kún inu awọn eniyan Rẹ̀, Ẹmi nì maa n mu idalẹbi wá sinu ọkàn awọn ti ko i ti i ri igbala. Ẹgbẹẹdogun eniyan ti o gbọ́ iwaasu Peteru ni Ọjọ Pẹntekọsti ni o ni igbọgbẹ ọkàn fun ẹ̀ṣẹ wọn ti wọn si bèère ohun ti wọn yoo ṣe ki wọn le ri igbala. Wọn gba gbogbo nnkan ti Peteru sọ gbọ́, wọn si gbọran si ẹkọ rẹ, wọn si yọ̀ ninu itujade Ẹmi Ọlọrun.

Awọn miiran gbagbọ́ pe a tú Ẹmi Mimọ́ jade ni Ọjọ Pẹntekọsti lati fi ipilẹ Ijọ lelẹ ati pe ko tun ṣe ohun danindanin fun awọn ẹlomiran lati ri i gbà. Ṣugbọn eyi lodi si ẹkọ Peteru tabi ti Paulu. Ọpọlọpọ ọdun lẹyin Pẹntekọsti ni a ri Peteru nigba ti o lọ si ile Kọrneliu, Keferi, ẹni ti o ri Ẹmi Mimọ́ gbà. Ohun ti asọtẹlẹ wi ni pe **eniyan gbogbo**. "Nitoripe ninu Ẹmi kan li a ti baptisi gbogbo wa sinu ara kan, iba ṣe Ju, tabi Hellene, iba ṣe ẹrú, tabi omnira; a si ti mú gbogbo wa mu ninu Ẹmi kan" (1 Kọrinti 12:13). Lẹyin eyi, nigba ti Paulu wà ni Kọrinti, awọn mejila ni Ẹmi Mimọ bà lé (Iṣe Awọn Apọsteli 19).

Eyi ni Akọ́rọ̀ Ojo. Joẹli tun sọ nipa Arọkuro Ojo ti yoo rọ̀ ni oṣu kin-in-ni (oṣu April gẹgẹ bi kika oṣu awọn Ju). Peteru ni ileri naa jẹ ti awọn eniyan naa ni Ọjọ Pẹntekọsti, ṣugbọn pẹlu "fun awọn ọmọ nyin, ati fun gbogbo awọn ti o jìna rére, ani gbogbo awọn ti Oluwa Ọlọrun wa ó pè" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:39). Nitori náà akoko kan n bọ nigba naa "ti o jìna rére," nigba ti Ojo Arọkuro yoo tú jade.

Ijọ la Igba Okunkun kọja, ati fun ọpọlọpọ ọdun, kinun ni ojo ti ẹmi ti o rọ̀ sori ilẹ aye. Ojo ti ara paapaa kò tilẹ rọ̀ sori ilẹ Palẹstini. Pupọ ninu ilẹ naa ni o di aṣalẹ.

### Ojo ni Palẹstini

Lẹyin eyi ni iwọn ọdun 1900, ikuuku bẹrẹ si i sọkalẹ sori Ilẹ Mimọ́. Yoo ha jẹ pe aṣalẹ naa yoo tun rú ewé tutu yọ̀yọ̀ jade? Nigba ti Ojo Arọkuro ti Ẹmi bẹrẹ si i rọ ni ọdun 1906, ọpọlọpọ ojo ti ara bẹrẹ si i rọ ni Palẹstini, ilẹ wọn si bẹrẹ si i mu ọpọlọpọ eso daradara jade wa. Eso oko ilẹ yii ti gba ẹbun nigba kan ninu ayẹwo awọn eso oko ti gbogbo agbaye.

Ilẹ iyanrin gbigbẹ Palẹstini ti poungbẹ fun ojo; bakan náà ni awọn Onigbagbọ́ lati ibẹrẹ ọdun 1900 poungbẹ fun Ẹmi Ọlọrun si i.

### Isọji Ẹmi

Martin Luther ti kọ́ otitọ ni pe "Olododo yio yè nipa igbagbọ́." O ti ṣiwọ kuro ninu pipọn ara rẹ̀ loju fun ẹ̀ṣẹ rẹ̀, o si ti ri idalare gbà, nipa ironupiwada si Ọlọrun. Laaarin ọpọlọpọ inunibini, o jẹ oloootọ sibẹ si ipe Ọlọrun, o si ṣe ifilọlẹ Ayipada Ijẹwọ Igbagbọ́.

Lẹyin eyi John Wesley woye pe ẹkọ Isọdimimọ wà fun awọn eniyan igba isisiyii, gẹgẹ bi Jesu ti gbadura: "Sọ wọn di mimọ́ ninu otitọ … kì si iṣe kìki awọn wọnyi ni mo ngbadura fun, ṣugbọn fun awọn pẹlu ti yio gbà mi gbọ́ nipa ọ̀rọ wọn" (Johannu 17:17-20). Orukọ miiran ti a n pe isọdimimọ ni iwa mimọ́. Ọpọlọpọ eniyan gba ẹkọ John Wesley; lẹyin ti a si ti dari ẹ̀ṣẹ wọn ji wọn nigba ti a da wọn lare, wọn wá isọdimimọ a si mu ẹda ẹ̀ṣẹ kuro ninu ọkàn. Nigba ti Adamu dẹṣẹ ninu Ọgbà, o mu ẹda ẹ̀ṣẹ wá sinu olukuluku eniyan. Ko ṣe e ṣe fun wa pe ki a má bí wa pẹlu ẹda ẹṣẹ ti Adamu ninu wa ṣugbọn a le yọ ọ kuro ninu wa nipa isọdimimọ, iṣẹ oore-ọfẹ keji ti o n ṣẹlẹ nipa Ẹjẹ Jesu. Nigba naa ni ọkàn yoo jẹ mimọ́ yoo si wa ni imurasilẹ lati gba ifiwọni Ẹmi Mimọ́.

**Ọkàn ti Ebi n Pa**

Ọpọlọpọ eniyan ni o wà ni aye ṣaaju ọdun 1906, awọn ti a wẹ ọkàn wọn mọ́, wọn si n fi itara gbadura pe ki Ọlọrun rán Ẹmi Mimọ lati fi wọ̀ wọn. Ọkan wọn dabi ilẹ ti o gbẹ ti a si ti gbin eso si ti o n reti ojo lati mu ki eso naa hù.

Awọn eniyan n pade ni ẹgbẹẹgbẹ ni oriṣiriṣi ijọ lati gbadura fun Ojo Arọkuro. Ijọ kọọkan rò pe awọn ni yoo kọkọ ri Ileri naa gbà, ṣugbọn ki yoo wá sọdọ ẹgbẹ kan pataki. A tu Ẹmi naa jade sori ọkàn kọọkan ti o jẹ mimọ ati alaileeri.

**Ojo Arọkuro**

Ni ọjọ kẹsan-an oṣu April ni ọdun 1906, oṣu kin-in-ni gẹgẹ bi kika oṣu ti awọn Ju, gẹgẹ bi Joẹli ti sọtẹlẹ, Ẹmi Mimọ sọkalẹ sori awọn ẹgbẹ onirẹlẹ kekere kan ti o pejọ pọ lati wa Oluwa ninu ile kekere kan ni Bonnie Brae Street, ni Lọs Angeles. Awọn eniyan ri Ẹmi Mimọ́ gbà gẹgẹ bi o ti ri ni Ọjọ Pẹntekọsti, wọn si sọrọ ni oriṣiriṣi èdè gẹgẹ bi Ẹmi Mimọ́ ti fun wọn ni ohùn. Wò o bi inu wọn ti dun to pe a kà wọn yẹ lati ri Ẹbun yii gbà lati Oke! Iyin kun inu ọkàn wọn ni akunwọsilẹ. Lai pẹ iroyin de lati ilẹ miiran gbogbo pe Ẹmi Mimọ ti ba le awọn ti a ti sọdimimọ ni tootọ. Dajudaju ilẹ le ni inu didun ki o si yọ̀, nitori Ọlọrun ti tú Ojo Arọkuro jade.

**Ifedefọ Eke**

Ọpọlọpọ eniyan lonii ni o n wi pe awọn n fi ède fọ̀, ṣugbọn wọn ko ni agbara lati gbé igbesi-ayé iwa mimọ́, ki a ma ṣẹṣẹ wa sọ pe ki wọn jẹ ẹlẹri Ihinrere tootọ ti Jesu Kristi. Satani ti rán itanjẹ sinu ayé, awọn eniyan si n gba eke gbọ́, wọn si n ri agbara ẹmi eke gbà, nitori wọn ko fẹ jẹwọ ẹ̀ṣẹ ti o wà ninu igbesi-ayé wọn.

Ẹmi Mimọ́, Adaba jẹjẹ nì ti a le tete mu binu, ki yoo wá sinu ohun-elo aimọ́. A maa ṣe ibugbe Rẹ̀ ninu ọkàn ti a ti sọdimimọ patapata.

**Ọkàn ti a ti Sọdimimọ́**

Fun bi eyi ti o ju ogoji ọdun sẹyin ni Ojo yii ti n rọ̀. Nibikibi ti Oluwa ba ri ọkàn kan ti a ti sọdimimọ ti o si kún fun ifararubọ ti o si n poungbẹ fun Ẹmi Mimọ́, Oun a maa rán Olutunu lati ba a gbé. Ẹmi Ọlọrun n pese Iyawo fun Ọmọ Ọlọrun, Ẹni ti yoo pada lai pẹ lati wa mú awọn ti Rẹ̀. Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ni aṣọ igbeyawo naa ti o jẹ pe ẹnikẹni ti ko ba ni in ki yoo le ni ipin ninu Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan.

Ina Ẹmi Mimọ́, Ororo Ayọ̀, n jò ninu ọkàn Iyawo Kristi. Olukuluku ẹni ti o ba ṣe ifararubọ ni o ni anfaani lati gbadun ibukun atokewa yii. “Nitori ijọba Ọlọrun kì iṣe jijẹ ati mimu; bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ ninu Ẹmí Mimọ́” (Romu 14:17).

**AWỌN IBEERE**

1. Iru ipo wo ni awọn Ọmọ Israẹli wà ni akoko Joẹli?
2. Ileri wo ni o ṣe?
3. Nigba wo ni a kọkọ tú Ẹmi Mimọ́ jade, ki ni a si pe itujade Ẹmi yii?
4. Nigba wo ni a tú Ojo Arọkuro dà silẹ?
5. Ta ni ẹni ti o ni ẹtọ lati ri ifiwọni Ẹmi Mimọ́ gbà?
6. Ta ni Iyawo Kristi?